# Lítíréṣọ̀ Yorùbá, Ọ̀rọ̀ Ààbò àti Ìdàgbàsókè Orílẹ̀-Èdè

**Olúyẹ́misi Adébọ̀wálé**
*Department of Linguistics and Nigerian Languages*
*Adékúnlé Ajáṣin University, Àkùngbá-Àkókó*
*yemisiadebowale@yahoo.co.uk*

## Ìfáárà

Ọ̀rọ̀ ààbò ṣe pàtàki púpọ̀ nínú ìgbé ayé láwùjọ ẹ̀dá. Ààbò ṣe kókó tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ tí kò sí ẹ̀dá alàyè tó ń fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú un; kò sì sí ẹ̀yà kan, orílẹ̀ tàbí àwùjọ tó kóyán ààbò kéré. A ṣe àkíyèsí pé kò lè sí ìtẹ̀síwájú níbi tí ìpayà, rògbòdìyàn àti àìbàlẹ̀ọ̀kan bá wà. Bí a ò bá ní jayò pa, a lè sọ pé ètò ààbò jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ohun tó gbé awùjọ ró.

Àwọn onímọ̀ bí i Olúfàjọ (1988), Adébọ̀wálé (1991), Ògúnṣínà (1992), Adébọ̀wálé (1995), Adébọ̀wálé àti Adéjùmọ̀ (1996), Ìṣọ̀lá (1998) àti Adéjùmọ̀ (1999) ti ṣiṣẹ́ lórí ọ̀ràn dídá nínú iṣẹ́-ọnà ṣùgbọ́n wọn kò tẹpẹlẹ mọ́ àjọṣepọ̀ tí èyí ní pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ààbò àwùjọ. Táíwò (2013) tó ṣe àgbéyẹ̀wò àfihàn ètò ààbò nínú Ká Rìn, Ká Pọ̀ tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí kọ sọ ọ́ di mímọ̀ pé ìwòye òǹkọ̀wé nípa ọ̀ràn dídá ní àsìkò ìṣèjọba alágbádá ẹlẹ́ẹ̀kẹta ti orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ló bí ìwé náà. Táíwò ṣe àlàyé pé ṣe ni Òkédìjí fi ìtàn inú Ká Rìn, Ká Pọ̀ ṣí aṣọ lójú eégún àrà ọ̀tọ̀ tí àwọn ọ̀daràn ń gbà lo ohun èlò ìgbàlódé láti máa dúnkòokò mọ́ ará ìlú. Bákan náà ló sọ ipa tí ìdàgbàsókè ìmọ̀ ẹ̀rọ gbà ṣe àkóbá fún

Nàìjíríà. Àwọn onímọ̀ kò tí ì yẹ ọ̀rọ̀ ààbò wò nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá léte àtimọ ohun tí àwọn òǹkọ̀wé sọ nípa rẹ̀; èyí ni yóò jẹ́ kí àpilẹ̀kọ yìí tú iṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò lórí kókó-ọ̀rọ̀ yìí.

Nínú àpilẹ̀kọ yìí ni a ó ti gbìyànjú láti ṣe àyẹ̀wò ètò ààbò àti oríṣiríṣi ohun tí a lè dáàbò bò ní àwùjọ Yorùbá àti ìhà tí wọ́n kọ sí i. Bákan náà ni a ó wo ipa tí ìṣọ̀wọ́ àwọn tí èto ààbò wà lọ́wọ́ rẹ̀ ń kó, a ó sì ṣe àyẹ̀wò oríṣiríṣi ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà ṣe ètò ààbò gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá. Tíọ́rì ìmọ̀ ìbáraẹnigbépọ̀ ni a lò láti fi ṣe àyẹ̀wò náà. Tíọ́rì ìmọ̀ ìbáraẹnigbépọ̀ níí ṣe pẹ̀lú ìmọ̀ nípa ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin lítíréṣọ̀ àti àwùjọ. Bámidélé (2000:16) sì ti tọ́ka sí i bí Bonald ṣe wòye pé bí a bá farabalẹ̀ ṣe àyẹ̀wò lítíréṣọ̀ orílẹ̀-èdè kan, a ó ní ìmọ̀ kíkún nípa àwọn ènìyàn ibẹ̀. Bí a bá sì wo ìsọ̀rí tíọ́rì ìmọ̀ ìbáraẹnigbépọ̀ tó tẹpẹlẹ mọ́ yíyàwòrán ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń lọ láwùjọ, yóò ran láméyítọ́ lọ́wọ́ láti lè wo iṣẹ́-ọnà tó ń tú palẹ̀ mọ́ àwùjọ tó bí iṣẹ́-ọnà bẹ́ẹ̀.

## Ohun tí ààbò jẹ́

Ètò ààbò ní í ṣe pẹ̀lú ìgbésẹ̀ tí a gbé láti rí i pé a dáàbò bo ẹ̀mí tàbí dúkìá. Ọ̀rọ̀ nípa ààbò jẹ mọ́ kí á ṣe ètò gúnmọ́ nípa ìwàlálàáfíà àti ìgbé ayé àìléwu fún àwọn ènìyàn tó wà ní àwùjọ. Ó jẹ mọ́ bíbọ́ lọ́wọ́ ewu àti ohun tó lè fa ìpalára àti ìdúnkòokò mọ́ ni. Bí a bá rí àwùjọ tí a bá ti ṣe ètò ààbò tó nípọn, a ó ṣe àkíyèsí pé kì í sí ìpayà ogun, ọ̀tẹ̀, ìfipájalè, ìdigunjalè, ìjínigbé,

ìfi-nǹkan-ìní-ṣòfò tàbí ewukéwu tó lè mú àìbalẹ̀ ọkàn bá àwọn olùgbé àwùjọ bẹ́ẹ̀.

Ètò ààbò tún ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀nà tí ẹnì kan tàbí ọ̀pọ̀ ènìyàn ń lò láti ṣọ́ ara tàbí dúkìá wọn. Irúfẹ́ ìṣọ́ra báyií lè jẹ mọ́ gbígbé ìgbésẹ̀ gúnmọ́ láti ṣe onírúurú ètò ààbò fún ara ẹni tàbí dúkìá ẹni nípa lílo oríṣiríṣi ohun èlò ìdáàbò bò. Bí a bá sì ń sọ̀rọ̀ nípa ọ̀rọ̀ ààbò, a ṣe àkíyèsí pé ó ṣe pàtàkì fún ìgbé ayé àlàáfíà, ètò ọrọ̀-ajé tó múná dóko àti ìbáṣepọ̀ gúnmọ́ láàrin oríṣìíríṣìí ìsọ̀rí ènìyàn àwùjọ, ìletò, ìlú, ìpínlẹ̀ àti orílẹ̀ èdè. Ibi tí kò bá ti sí ètò ààbò tó péye ni onírúurú ìwà ìbàjẹ́ ti ń gbèrú, tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ búburú, làásìgbò, ogun àti oríṣiríṣi ewu tó rọ̀ mọ́ ọn ti ń wáyé. Àwọn onímọ̀ nípa àwùjọ gbà pé ìfọ̀kànbalẹ̀ tó wà lórí ẹ̀mí àti dúkìá ènìyàn àwùjọ ló máa ń jẹ́ kí a mọ irú ipò àti ipa ọ̀rọ̀ ààbò ní àwùjọ bẹ́ẹ̀.

Ààbò ò fi bẹ́ẹ̀ péye mọ́ lode-òní tí ìjà ẹ̀sìn, ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti ètò ìṣèlú ìgbàlódé ti gbòde kan. Púpọ̀ àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá ló sì ti kọ̀wé láti fi bí ọ̀rọ̀ ààbò ṣe rí ní ọ̀rúndún kọkànlélógún tí a wà yìí hàn. Ohun kan tí ó sì hànde nínú iṣẹ́-ọnà wọn ni pé àwọn ènìyàn ní láti ṣetán láti fọwọ́sowọ́pọ̀ nípa bí ètò ààbò àwùjọ kò ṣe ní dàrú. Èyí fihàn pé ẹnìkọ̀ọ̀kan tó wà láwùjọ ló ní ipa pàtàkì tí yóò kó láti jẹ́ kí ètò ààbò bẹ̀ẹ̀ kẹ́sẹjárí.

### Oríṣiríṣi ọ̀nà ìdáàbòbò

Láti ìgbà tí aláyé ti dáyé ni ìran Yorùbá ti ń ṣètò ìdáàbòbò fún ara wọn, ohun ìní wọn àti ìlú wọn. Ògúnṣínà (2013) ti ṣe àlàyé

nípa bí Yorùbá ṣe ní ètò ààbò ara ẹni, ààbò ile, ààbò iṣẹ́, ààbò àdúgbò àti ààbò ìlú. Inú agbo-ilé ni ẹbí ń gbé ní àwùjọ Yorùbá àtijọ́ bẹ́ẹ̀ sì ni baálé-ilé ló máa ń ṣe àmójútó ètò ààbò nínú agbo-ilé kọ̀ọ̀kan. Àwọn mìíràn tó máa ń ran baálé lọ́wọ́ nínú ètò ìṣàkóso àti àmójútó ètò ààbò agbo-ilé ni ìyáálé-ilé, ọmọkùnrin-ilé, obìnrin-ilé àti àwọn ọmọ-oṣú ilé. Ọ̀kan pàtàkì nínú ohun tí àwọn Yorùbá fi ń ṣe ohun àmúṣagbára láti dáàbò bo agbo-ilé wọn nígbà náà ni àmì òrìṣà ìdílé àti ṣíṣe ojúbọ̀ òrìṣà bẹ́ẹ̀ sí ibi tí kò ṣe kọ́lọ́fín nínú agbo-ilé bẹ́ẹ̀. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé òrìṣà bẹ́ẹ̀ yóò máa bójútó àwọn ènìyàn àti ohun ìní wọn tó wà nínú agbo-ilé náà. Bákan náà ni wọn máa ń so àsokọ́ sí ẹnu ọ̀nà àbáwọlé ilé kọ̀ọ̀kan; wọn a sì tún máa ri òògùn mọ́ igun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ilé láti dáàbò bò ó. Kódà, wọn a máa gbé òkú àgbàlagbà jó yíká agbo-ilé kí wọ́n tó sin òkú bẹ́ẹ̀ kí ó lè wo gbogbo agbo-ilé tí yóò máa dáàbò bò lẹ́yìn tí ó bá wọ ilẹ̀ sùn.

Bí a ṣe ń gbé ìgbésẹ̀ láti dáàbò bo ilé náà ni à ń ṣètò láti dáàbò bo ìlú. Ọba tó ba lórí ohun gbogbo ni olórí tó máa ń ṣètò ààbò ìlú. A ní láti fi kún un pé ètò ààbò ti wà fún owó tí a fi pamọ́ sí báǹkì ìgbàlódé, ètò ààbò tún ti wà fún ọkọ̀. Bákan náà ni ọ̀nà ìgbà-dáàbò-bo nǹkan láyé òde-òní ti yàtọ̀ sí ti ayé àtijọ́. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé a ṣì ń lo lára ohun èlò ìdáàbò bò ti ìbílẹ̀, ọ̀pọ̀ nǹkan ni àwọn ènìyàn fi ń ṣètò ààbò láwùjọ òde-òní.

## Ohun èlò ààbò

Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú Adéoyè (2005), lára ohun tí àwọn ará àtijọ́ ń lò láti dáàbò bo ara àti láti gba ara wọn sílẹ̀ bí ewu bá wà ni òkò sísọ, kùmọ̀ jíjù, àdá, ọfà títa, ìbọn ṣakabùlà àti ara dídì nípa òògùn. Ògúnṣínà (2013) mẹ́nubà á pé Yorùbá máa ń lo àgbo, ońdè, òrùka ẹ̀rẹ, ẹbọ rírú, ètùtù ṣíṣe àti oríṣiríṣi òògùn mìíràn láti fi ṣètò ìdáàbò bò.

Lára ìgbésẹ̀ tí àwọn Yorùbá máa ń gbé láti ṣe ètò fún ààbò ìlú láyé àtijọ́ ni mímọ odi yí ìlú ká láti dènà kí àwọn ọ̀tá má bà á rí àyè gbà wọ ìlú, ìlò amí, èèwọ̀, àrokò, ṣíṣe àmúlò alóre tí yóò máa wo àwọn tó ń wọlé àti àwọn tó ń jáde ní ìlú, tí yóò sì máa ta ìlú lólobó bí ó bá kófìrí pé ewu wà. Àwọn irọ̀ ìgìrìpá àti irọ̀ àgbà ló máa bójútó ètò ààbò ìlú láyé àtijọ́. Nínú irọ̀ ìgìrìpá ni wọ́n ti ń yan púpọ̀ nínú àwọn ẹ̀ṣọ́ tó ń ṣe àmójútó ààbò ìlú. Bí a bá sì wo àwùjọ Yorùbá ayé àtijọ́, a ó ṣe àkíyèsí pé àwọn irọ̀ ìgìrìpá ló ń ṣe iṣẹ́ ọdẹ aṣọ́de tí wọ́n sì ń gba ìlú sílẹ̀ lọ́wọ́ àwọn olè àti arúfin. Bákan náà ni àwọn ọ̀dọ́ pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ àti àtìlẹyìn àwọn àgbà máa ń dáàbò bo ìlú lásìkò ogun. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni Yorùbá a tún máa lo òògùn láti dáàbò bo ìlú wọn, wọ́n sì sáábà máa ń ri òògùn mọ́ àwọn ọ̀nà tó wọ ìlú láti dènà ìkọlù ogun àti àjàkálẹ̀ àrùn. Arówóṣẹgbẹ́ (2012: 103 -105) fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé onírúurú ètùtù ni àwọn obìnrin máa ń ṣe láti rí i pé àláfíà pípé àti ààbò tó dájú wà fún gbogbo ará ìlú.

Gbogbo nǹkan tìbílẹ̀ wọ̀nyí ni àwọn ènìyàn kan ṣì ń lò láti fi dáàbò bo ara wọn àti ohun ìní wọn, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun

èlò ìgbàlódé ló wà tí àwọn ènìyàn ń lò fún ètò ààbò báyìí. Àwọn kan a máa gba *tọ̀ọ̀gì* aláàbò, ọdẹ aṣọ́lé, ọdẹ aṣọ́géètì, ṣíṣe irin bọ́gílárì sí ojú fèrèsé, lílo ilẹ̀kùn onírín, lílo ìbọn, àdá, àtíkè tajútajú, ẹ̀rọ agbohùnsílẹ̀ ìgbàlódé, lílo àjọ adójútòfò, lílo owó, ìṣàmúlò àdó olóró láti rẹ́yìn ẹni tí a lérò pé ó lè pa ètò ààbò wa lára àti oríṣiríṣi ohun èlò bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Òkédìjí sọ̀rọ̀ nípa ìlò ìbọn fún ààbò ara ẹni, ó hàn gbangba nínú ìmọ̀ràn tí dókítà gba Lápàdé pé níní ìbọn àti lílò ó kò ṣe é gbẹ́kẹ̀lé tó bẹ́ẹ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ:

> ... má sọ pé o gbẹ́kẹ̀ lé ààbò ìbọn ... ẹran tá a fójú
> rí ló ṣe é tàbọn sí o, ìbọn ò ran atẹ́gun o, òfúurufú
> ò ṣe é yìnbọn sí. (*Ká Rìn, Ká Pọ̀,* o.i 60)

Bẹ́ẹ̀ sì ni lílo irin àjólé sí fèrèsé yàrá tí a fi hàn nínú *Ká Rin Ká Pọ̀* kò dènà kí àwọn ọ̀daràn má ta ọgbọ́n tí wọn yóò fi já a. Adékẹ́yè sì fi hàn nínú *Kò sí Látẹ* (o.i 72 -73) pé àwọn ojú fèrèsé a máa ṣe ìdíwọ́ láti yọjú síta wo ẹni tó bá ń gbé ìgbésè tó lè ṣàkóbá fún ààbò ìlera ẹni. Ìlo ẹ̀rọ agbohùnsílẹ̀ ìgbàlódé ló ran Àmíná lọ́wọ́ tó fi rí àṣírí ètò ààbò tí àwọn olè ṣe fúnrawọn nínú *Oyin Inú Àpáta*, èyí sì ni kò jẹ́ kí Àmíná tó ń ṣe amí fún ọlọ́pàá rí ìpalára níbi tó ti ń dọ́gbọ́n wádìí wọn. Òǹkọ̀wé tún fi hàn nínú *Oyin Inú Àpáta* pé ó dára kí á ṣètò ààbò fún ohun ìní wa lọ́dọ̀ àjọ adójútòfò tí yóò sanwó padà fún wa bí ètò ààbò ohun tí a fi sí ìpamọ́ bẹ́ẹ̀ bá yingin. Irúfẹ́ èyí ló wáyé nígbà tí àjọ náà ṣètò láti san owó fún oníbààrà tí ó ní owó sí ilé ìfowópamọ́ tí adigunjalè jí gbogbo owó rẹ̀ kó. Onírúurú ìsọ̀rí ènìyàn máa ń lo

*tọ̀ọ̀gì* tí yóò máa ṣọ́ wọn tàbí tí yóò bá wọn dá sẹ̀ríà fún àwọn tí wọ́n lérò pé ó le ṣe àkóbá fún ètò ààbò wọn gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú *Ọ̀tẹ̀ Nìbò, Kò Sáyè Lááfin, Ọ̀tafàsókè!, Kẹ́ṣinlóró, Ọ̀gá Tíṣà* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lílo ọdẹ aṣọ́géètì láti bójútó ààbò ilé tàbí ibi iṣẹ́ kì í ṣe òògùn ajẹ́bíidán fún ààbò ara ẹni àti ilé ẹni nítorí pé àwọn ènìyàn bẹ́ẹ̀ lè gbàbọ̀dè ti ọ̀gá tó ń ṣọ́ ilé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Òkédìjí ṣe fi hàn pé gbogbo wàhálà, ìdààmú àti ìpòrúurù ọkàn ti Mánijà báǹkì là kọ́ja nínú *Ká Rìn, Ká Pọ̀* kò ṣẹ̀yìn bàbá aṣọ́géètì rẹ̀.

## Àfihàn Ètò Ààbò nínú Lítíréṣọ̀

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ọ̀nà tí a fi ń ṣe ètò nípa ọ̀rọ̀ ààbò ni àwọn òǹkọ̀wé ṣe àfihàn nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ohun tí èyí sì fi hàn ni pé èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́ bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni a lè lo lítíréṣọ̀ láti la àwọn ènìyàn lọ́yẹ̀ nípa onírúurú nǹkan tó lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fún bí ó ṣe yẹ kí á tẹpẹlẹ mọ́ oríṣiríṣi ipele ààbò tó wà.

## Ọ̀rọ̀ ààbò nínú Lítíréṣọ̀ Alohùn

Bí a bá ṣe àyẹ̀wò Lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, a ó rí i pé wọ́n káràmásìkí ọ̀rọ̀ ààbò láwùjọ. A rí ìhà tí Yorùbá kọ sí ọ̀rọ̀ ààbò nínú òwe wọn. Lára irú òwe bẹ́ẹ̀ ni a ti fa àpẹẹrẹ wọ̀nyí yọ nínú ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ òwe bẹ́ẹ̀ tó wà:

1. Gungigungi ṣọ́gi gùn kó o má ba à gungi aládi.
2. Ọ̀bẹ ń ba ilé ara rẹ̀ jẹ́, ó ní òun ń ba àkọ̀ jẹ́.
3. Ojú lalákàn fi ń ṣọ́rí.
4. Àgbàrá kò ní òun ò nílé wó, onílé ni ò ní gbà fun un.
5. Igi ganganran má gún mi lójú, òkèèrè la ti í wò ó.

Bí a bá wo àpẹẹrẹ òwe òkè wọ̀nyí, a ó ṣe àkíyèsí pé wọ́n ń ṣe ìkìlọ̀ tó le mú ni bọ́ nínú wàhálà kan tàbí òmíràn; bẹ́ẹ̀ sì ni wọ́n tún ń ṣe ìpè fún ìkọbiara sí nǹkan lákòókò lọ́nà tí ewu kò fi ni wu ènìyàn. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ èèwọ̀ Yorùbá náà tún máa ń ṣe ìkìlọ̀ tó fi bí Yorùbá ṣe káràmásìkí ètò ààbò tí yóò mú kí ìgbé ayé dẹrùn fún tẹrú-tọmọ láwùjọ. Ìsọ̀rí èèwọ̀ kan wà tí a lè sọ pé ó rọ̀ mọ́ ààbò ara ẹni. Irúfẹ́ èèwọ̀ yìí ni èèwọ̀ bí i:

1. A kò gbọ́dọ̀ jókòó jẹun ní ẹnu ọ̀nà.
   Bí a bá jókòó jẹun ní ẹnu ọ̀nà, a kò níí yó.
2. Ìtọ̀ ọmọ kò gbọ́dọ̀ ṣàn pàdé ti ìyá rẹ̀ bí àwọn méjèèjì bá ń tọ̀ọ́lé.
   Bí ó bá pàdé, ọmọ náà yóò kú.
3. A kò gbọ́dọ̀ só sínú odó.
   Bí a bá só sínú odó, ẹni náà yóò kú.
4. A kò gbọ́dọ̀ jẹ irun orí.
   Bí a bá jẹ ẹ́, ẹni náà yóò kú.
5. Ènìyàn kò gbọ́dọ̀ jẹ kókò tútù.
   Bí a bá jẹ kókò tutu, ọ̀fun yóò máa hún olúwarẹ̀, kò sì ní ní àlàáfíà.

Irúfẹ́ èèwọ̀ òkè wọ̀nyí àti oríṣi mìíràn bẹ́ẹ̀ ń ṣe ìkìlọ̀ tí kò ní jẹ́ kí ètò ààbò ara ẹni àti ti tẹbí-tará yingin bí a bá pa wọ́n mọ́. Yàtọ̀ sí ìlò òwe àti èèwọ̀ tó wà fún ààbò ara ẹni, àwọn Yorùbá a tún máa ṣe oríṣirìṣi òògùn ìṣọ́ra. Irúfẹ́ òògùn bẹ́ẹ̀ ni sísín gbẹ́rẹ́, lílo ońdè, ṣíṣe òògùn òkígbẹ́ tí kò fi ní jẹ́ kí àdá tàbí ìbọn ranni. Lọ́pọ̀ ìgbà

sì ni ẹni tí yóò lo òògùn ìṣọ́ra wọ̀nyí ní láti ṣe àmúlò ọfọ̀ tàbí ògèdè tó jẹ́ ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ alohùn kí òògùn bẹ́ẹ̀ tó jẹ́.

Bí a bá wo àlọ́ onítàn, a ó ṣe àkíyèsí pé a rí ìpàrokò ètò ààbò nípele nípele. Kò fi bẹ́ẹ̀ sí ìdàrúdàpọ̀ nínú àwùjọ tí a yàwòrán rẹ̀ nínú àlọ́ onítàn ṣùgbọ́n ibi yòówù tí ọ̀kan nínú ẹ̀dá-ìtàn tí a fi pàrokò ìwà ẹ̀dá tó bá tasẹ̀ àgẹ̀rẹ̀ láti ṣe ohun tó lè dá rúgúdù tó ń mú ìpayà bá ni ni àwọn ènìyàn yóò ti fi ẹjọ́ ẹni bẹ́ẹ̀ sun ọba. Kíá ni ọba yóò ṣe ètò láti pe ẹni tí a fẹ̀sùn kàn láti wá jẹ́jọ́. Ìgbésẹ̀ tí ọba máa ń gbé pẹ̀lú àwọn ìjòyè rẹ̀ nínú àlọ́ inú *Ojú Ọ̀ṣùpá: Apá Kìíní* àti *Apá Kejì, Àlọ́ Àpagbè, Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn* àti *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè* máa ń jẹ́ kí ọkàn àwọn aráàlú balẹ̀ lórí ètò ààbò, wọ́n ó sì máa gbé láìsí ẹ̀rù tàbí ìfòyà. Ṣùgbọ́n bí àwọn ènìyàn kò bá rí ìdánilójú pé ẹ̀mí wọn dè, wọn a máa fi ìlú sílẹ̀ lọ sí ibi tí ọkàn wọn yóò ti balẹ̀. Ènìyàn yóò túbọ̀ pọ̀ sí i ní ìlú tí ààbò tó dájú wà; ètò ọ̀rọ̀-ajé wọn yóò sì tún gbèrú sí i, ṣùgbọ́n èrò ìlú tí wọ́n bá fi sílẹ̀ máa ń dínkù; iná ètò ọ̀rọ̀-ajé wọn á sì jó àjórẹ̀yìn.

## Ètò ààbò nínú Lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ

Ohun tí ó wà láwùjọ tí àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá fi hàn níbi gbogbo tí ọ̀rọ̀ ìṣàkóso ìlú bá ti jẹyọ nínú iṣẹ́-ọnà wọn ni pé àwọn ìjòyè ìlú, ìjòyè àdúgbò, jagunjagun, ọdẹ àti onírúurú ìsọ̀rí ènìyàn mìíràn ló máa ń fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú ọba láti ṣe àmójútó ààbò tó péye fún ìlú.

Ìsọ̀rí òǹkọ̀wé kan wà tó ṣe àfihàn ètò ààbò ayé àtijọ́ nínú iṣẹ́-ọnà wọn. Ọ̀kan lára òǹkọ̀wé bẹ́ẹ̀ ni Fálétí tó kọ *Ogun Àwítẹ́lẹ̀*. Òǹkọ̀wé yìí fi hàn nínú iṣẹ́-ọnà rẹ̀ yìí pé ọba tàbí baálẹ̀ ni olórí ìlú; àwọn ọdẹ àti jagunjagun ló sì máa ń ràn án lọ́wọ́ láti bójútó ààbò ìlú. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé àwọn ni baálẹ̀ ránṣẹ́ pè nígbà tí àwọn adigunjalè kọ̀wé pé àwọn ń bọ̀ wá ja ìlú wọn lólè. Bí àwọn ọdẹ àti jagunjagun ṣe ń gbáradì láti dáàbò bo ìlú wọn ni wọ́n tún ń ṣe onírúurú ètò tí wọn ó fi ró ara wọn kí wọ́n má bà á bá ogun àwítẹ́lẹ̀ tó fẹ́ ja ìlú wọn rìn. Wọ́n dá Ifá láti mọ ọjọ́ tí àwọn olè náà yóò wọ ìlú, wọ́n ṣètò fèrè, egbòogi, oríṣiríṣi òògùn mìíràn bí àkáàbá, àgádágodo, àdá, ìbọn pẹ̀lú ọta àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀tù. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni wọ́n sín àìmoye gbẹ́rẹ́ tí wọ́n sì kọ́ ìlò ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ọfọ̀ àti ògèdè. Bákan náà ni àwọn olè náà dira ogun nípa lílo òògùn ìṣújú, oǹdè, ẹ̀wù egbòogi, ìyá odó ńlá tí obìnrin kan rù ṣáájú wọn, àdá, ìbọn àti ẹ̀tù kí apá àwọn ọdẹ má ba à ká wọn. Àwọn ọdẹ ìlú tí wọ́n fẹ́ lọ jà lólè náà kò túraká nítorí wọ́n tún ṣètò bí wọn ó ṣe máa dúró sí ẹnu ìloro ìlú àti àwọn bodè tó wọ ìlú. Ọ̀nà mẹ́fà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni àwọn ọdẹ pín ara wọn sí láti bójútó ààbò ìlú kí àwọn olè tó fẹ́ wá jà wọ́n má ba à rí àyè wọ inú ìlú wọn. Nígbà tí àwọn ọdẹ tó ń ṣọ́ ìlú àti àwọn olè tó fẹ́ kó ìlú kọlura, wọn fi ìjà pẹ́ẹ́ta, ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan sì bẹ̀rẹ̀ sí lo ohun àmúṣagbára tí wọ́n ní. Ìpinnu, ìforítì àti ìdánilójú pé ọdẹ ni wọ́n ló jẹ kí wọ́n borí olè tó gbọ̀nà ẹ̀bùrú wọ̀lú láti wá kó wọn lẹ́rù.

Ipele méjì ni òǹkọ̀wé *Ògún Lákáayé* gba wo ìgbésẹ̀ tí a gbé láti dáàbò bo ìlú kí ọ̀tá má ba à rí àyè wọbẹ̀. Ọba ìlú ránṣẹ́

pe Ògún tó jẹ́ akíkanjú láti jẹ́ adarí ogun tí yóò lé ọ̀tá sẹ́yìn kí ogun má ba à wọ ìlú. A ṣe àkíyèsí pé lẹ́yìn tí Ògún ti lé ogun ẹ̀yìn odi sẹ́yìn ni òun fúnrarẹ̀ tún bẹ̀rẹ̀ sí dààmú ìlú tí kò jẹ́ kí wọ́n fi ẹ̀dọ̀ lórí òrónro, èyí ni pé ó ṣe ètò tí ogun ilẹ̀ ilé fi ń ja ìlú tí ó gbà kúrò lọ́wọ́ ìpaya ogun ẹ̀yìn odi. Ohun kan tí òǹkọ̀wé pe àkíyèsí sí nínú *Ògún Lákáayé* ni pé kò sí ohun tó yẹ kó da ètò ààbò gbogbo ìlú rú; ìbáà jẹ ogun ọ̀tá òde tàbí ti ọ̀tá ilé. Ìdí nìyí tí ìlú fí gbé ìgbésẹ̀ láti lo amí àti owó láti wádìí ohun tí wọ́n lè ṣe kí wọ́n fi ṣẹ́gun alágbára tó ń da ètò ààbò ìlú rú. Òrìṣàbùnmi, ìyàwó Ògún, tí inú rẹ̀ kò dùn sí bí ọkọ rẹ̀ ṣe ń fi òun nìkan sílẹ̀ sílé nígbà gbogbo tó bá jagun lọ ni ìlú fún lówó láti wádìí agbára Ògún kí wọ́n tó lè rẹ́yìn rẹ̀. Lẹ́yìn ìṣẹ́gun yìí ni ètò ààbò ìlú tó padà sípò tí àlàáfíà òun ìfọ̀kànbalẹ̀ sì jọba.

Ọ̀rọ̀ nípa ètò ààbò ìlú jẹ́ ọ̀kan nínú kókó-ọ̀rọ̀ tí Lásúnkànmí Tẹ̀là pe àkíyèsí sí nínú *Orogún Ọ̀dájú*. Ogun Ahóyaya tó ń ja ìlú Àńjùwọ́n kò jẹ́ kí ìfọ̀kànbalẹ̀ wà nílùú náà. Tọmọdé tàgbà, tọkùnrin tobìnrin ni ìdààmú dé bá nítorí bí àwọn ọ̀tá ẹ̀yìn odi ṣe ń jẹ wọ́n níyà tí wọ́n ń kó irè oko wọn tí wọ́n sì ń fipa bá àwọn obìnrin lò. Àwọn ọkùnrin tó sá fógun ni wọ́n tọ ọba ìlú wá láti ròyìn itú tí ọ̀tá ń pa tí wọ́n sì rọ̀ ọ́ láti gbé ìgbésẹ̀ bí àlàáfíà yóò ṣe padà bọ̀ sípò:

> Àwọn obìnrin tọ́wọ́ wọn bá tẹ̀ kì báà ṣọmọge tàbí adélébọ̀, àlò-wọ́dìí ni wọ́n ń fobìnrin ṣe. (o.i 74)

Kì í ṣe pé àwọn ọkùnrin náà káwọ́ gbera nítorí wọ́n ròyìn bí wọ́n ṣe gbé ìgbésẹ̀ ètò ààbò lọ́nà ìbílẹ̀ nípa lílé àwọn obìnrin wọn ní mágùn kí wọ́n fi lè rẹ́yìn odì:

> ... làwa bá tọwọ́ ilé, ọwọ́ àgbà bọ̀ ọ́ lábà wa. Ni a bá ń lé àwọn obìnrin wa, gbogbo wọn, àtọmọdé àtàgbà wọn, àtèyí tó bàlágà àtadélébọ̀ ni a gbé mágùn lé ara gbogbo wọn. Àárọ̀ yìí ni wọ́n ki àwọn obìnrin wa mọ́lẹ̀ ... gbogbo wọn ló fọrùn kọ́lẹ̀, tí wọ́n kú lọ rẹpẹtẹ torí abo ... (o.i 75)

Òǹkọ̀wé yìí jẹ́ kí á rí òye pé àwọn obìnrin ni ìyà máa ń jẹ jù bí ètò ààbò ìlú bá dàrú nítorí ìdààmú ìfipábánilò tí wọ́n máa ń kojú àti àdánù ọmọ àti ọkọ lásìkò ogun. Aṣojú àwọn ọkùnrin ìlú wá bẹ ọba láti wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣàdá lórí ọ̀nà tí wọn yóò gbà láti ṣẹ́gun ìpèníjà àwọn ọ̀tá tó wá ń bá wọn jà. Ìrànlọ́wọ́ àgbà ọdẹ kan tó ṣètò òògùn ìbílẹ̀ tí a fi ìtọ̀ obìnrin tí kò tí ì mọkùnrin ṣe ni ìlú Àńjùwọ̀n fi borí ogun tí ìlú Ahóyaya gbé tì wọ́n tí àlàáfíà sì padà jọba.

Kì í ṣe ètò ààbò ìlú nìkan ni àwọn òǹkọ̀wé máa ń tẹpẹlẹ mọ́, wọn a tún máa ṣe àfihàn ààbò ara ẹni. Ṣùgbọ́n ọ̀nà àrà tó jẹ mọ́ ìwà ọ̀daràn ni àwọn kan ń gbà láti ṣètò ààbò fúnra wọn lode-òní. Bí a bá wo *Oko* Aga (o.i 49- 50), a ó rí i bí àwọn kan tó pe ara wọn ní aláàánú ṣe dá ilé àánú tí wọ́n ti ń fi ẹ̀jẹ̀ ọ̀run ṣe òwò sílẹ̀ tí wọ́n sì kó àwọn ọ̀dọ́bìnrin jọ tó ń bímọ tí wọn yóò tà. Adégbóyègá tó jẹ́ gómìnà ìpínlẹ̀ Èbìtà tó yẹ kó jẹ́ alákòóso ètò ààbò ìpínlẹ̀ rẹ̀ kò ṣe iṣẹ́ rẹ̀ bí iṣẹ́, dípò bẹ́ẹ̀, ó ń gbé ìgbésẹ̀ tó ń pa ètò ààbò lára nígbà tí ó ṣètò bí àwọn awo yóò ṣe máa fi ẹ̀jẹ̀ ọmọ

jòjòló wẹ̀ ẹ́ lóṣooṣù. Bákan náà ni a tún rí òye pé àwùjọ òde-òní ti gba kí a máa ṣe ètò ààbò fún ọkọ̀. A rí àpẹẹrẹ èyí nínú *Oko Aga* (o.i 8) nígbà tí olè jí ọkọ̀ Bámidélé lọ tí ó sì kàn sí ilé-iṣẹ́ tí ó bá a ṣe ètò ààbò sára ọkọ̀ rẹ̀. Ètò ààbò tó ṣe fún ọkọ̀ rẹ̀ yìí ló jẹ́ kí àjọ tó ṣètò náà fi mú ọkọ̀ náà mọ́lẹ̀ ní Ṣàgámù tí àwọn ọlọ́pàá sì bá a rí i. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ òǹkọ̀wé ló tẹpẹlẹ mọ́ ọn pé àwọn ọ̀daràn máa ń ṣètò ààbò fúnra wọn ní ti ìlànà ìbílẹ̀. Oyè tó fẹ́ gbé ìyẹ̀fun olóró nínú *Àpótí Alákàrà* sín ara rẹ̀ ní gbẹ́rẹ́ yíká ara bẹ́ẹ̀ ló sì tún kọ́ ọfọ̀ àti ògèdè tí yóò pè bí nǹkan bá fẹ́ yíwọ́ ṣùgbọ́n pàbó ni akitiyan rẹ̀ já sí nítorí ìbọn àwọn aṣọ́bodè ló ṣekú pá a nígbà tí ó fẹ́ sá mọ́ wọn lọ́wọ́. Akilápá, tó jẹ́ ọ̀gá ọlọ́pàá náà wá ìrànlọ́wọ́ lọ sí ilé babaláwo tí yóò ṣe òògùn fún un láti fi pa ọ̀daràn kan àti Rìpẹ́tọ́ Kọ́lá tó fẹ́ tú àṣírí rẹ̀ pé ó ń ṣe onígbọ̀nwọ́ fún olè nínú *Oyin Inú Àpáta* ṣùgbọ́n ọwọ́ tẹ̀ ẹ́ kí ó tó rí òògùn náà sà. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́*, ọkùnrin tó ń ṣe ìṣekúṣe a máa ṣètò ààbò fúnrarẹ̀ ní ti ìlànà ìbílẹ̀ kí ó má ba à lùgbàdì obìnrin. Òǹkọ̀wé sọ ọ́ di mímọ̀ pé Fáladé tó kúndùn kíkó obìnrin gbé ìgbésẹ̀ láti dààbò bo ara rẹ̀ nípa wíwẹ̀ àgbo àti jíjẹ egbòogi. Bẹ́ẹ̀ ni Ojúlomi, oníṣègùn rẹ̀ fún un ní òrùka ọwọ́ àti tẹsẹ̀, ó sì kọ́ o ní oríṣiríṣi ọfọ̀ tí yóò máa lò. Àtubọ̀tán aájò yìí ni òǹkọ̀wé sọ di mímọ̀ nígbà tí ó ní:

> ...Bí o bá gbọ́wọ́ lé obìnrin níkùn kíà ni yóò mọ̀ bí a bá lé obìnrin náà ní mágùn... Bí májèlé bá wà nínú oúnjẹ tí wọ́n gbé fún un, kíá ni ọmọnílé kan yóò máa ju ìrù jòlòjòlò nínú oúnjẹ bẹ́ẹ̀... (o.i 12)

Òǹkọ̀wé kò ṣàìfi hàn pé ìwọ̀nba lagbára oògùn mọ nínú ètò ààbò ara ẹni tó ń ṣe ṣìná nítorí pé obìnrin ni yóò ṣekú pa irú ẹni bẹ́ẹ̀ níkẹyin gẹ́gẹ́ bí ti Fáladé tó fi ṣe àpẹẹrẹ.

Ojú tí àwọn òǹkọ̀wé kan fi wo ọ̀rọ̀ ààbò ní ọ̀rúndún kọkànlélógún yàtọ̀ sí ti àwọn òǹkọ̀wé ìṣáájú. Àwọn òǹkọ̀wé ìṣáájú tẹpẹlẹ mọ́ bí Yorùbá ṣe ń bójútó ọ̀rọ̀ ààbò ní àwùjọ wọn kí ọ̀làjú òde-òní tó dé. Àmọ́ báyìí, àyípadà ńlá ló ti dé bá ìhà tí àwọn òǹkọ̀wé kọ sí ọ̀rọ̀ ààbò ní àwùjọ wọn.

Omi tuntun ti ru, ẹja tuntun wọ̀lú ni ọ̀rọ̀ ààbò dà láwùjọ òde-òní. Onírúurú ìwà tí kò sí ní àwujọ Yorùbá ní ayé àtijọ́ ló ti gbòde kan lónìí. Èyí kò ṣàìní ṣe pẹ̀lú àyípadà ńlá tó dé bá ètò ọrọ̀-ajé, ìṣèlú àti akitiyan àwọn ènìyàn láti rí i pé kò sẹni tó kó tiwọn mẹ́rẹ̀. Tọmọdé tàgbà ló ń tiraka láti bẹ́gbẹ́ pé, èyí ló sì fa ìfigagbága tó pè fún ọ̀nà ọ̀tun láti ṣètò ààbò lórí ẹ̀mí, dúkìá àti àwùjọ lápapọ̀. Kò sí ohun tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ẹgbẹ́ òṣèlú àti ìbò dídì ní àwùjọ Yorùbá tẹ́lẹ̀. Kété tí ìṣèjọba olóṣèlú wọ̀lú ni àwọn tó ń díje fún ipò ti máa ń ta oríṣiríṣi ọgbọ́n láti ṣe ètò ààbò fúnra wọn kí àwọn alátakò má ba à dojú wọn bolẹ̀ lásìkò ìpolongo ìbò àti ọjọ́ ìdìbò. Ohun kan tí àwọn òǹkọ̀wé sì pe àkíyèsí sí nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá bí i *Ọ̀tẹ̀ Nìbò* tí Olú Owólabí kọ*, Ṣàngbá Fọ́!* tí Kọ́lá Akínlàdé kọ*, Kò Sáyè Láàfin* tí Lérè Adéyẹmi kọ*, Pelemọ* tí Débọ̀ Awẹ́ kọ*, Kẹ́ṣinlóró* tí Ọládẹ̀jọ Ọdẹ́bùnmi kọ*, Bọ̀bọ́ Àlútà* tí Olúṣẹ́gun Fátùrótì kọ, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ṣàfihàn bí àwọn tó fẹ́ gbé àpótí ìbò ṣe máa ń lo òògùn, ohun ìjà olóro àti tọ́ọ̀gì, bẹ́ẹ̀ ni

àwọn tó wà lórí àléèfà sì máa ń lo ọlọ́pàá láti dáàbò bo ara wọn àti láti dojú ìjà kọ àwọn alátakò. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìdààmú àti ìpayà máa ń bá àwọn ènìyàn lásìkò ìdìbò, àwọn òǹkọ̀wé fi hàn pé àlàáfíà máa ń padà sí àwùjọ lẹ́yìn ìdìbò, gbogbo nǹkan yóò sì padà bọ̀ sípò. Bákan náà ni ìjọba máa ń ṣe ètò ààbò fún àwọn ènìyàn tó jẹ́ olórí ìjọba. Bí a bá wo *Oko Aga,* a ó rí i pé àjọ aláàbò ṣètò ààbò fún gómìnà ìpínlẹ̀ Èbìtà. Kọ́lá ni òǹkọ̀wé fihàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀gá àgbà ní ẹ̀ka ààbò fún góminà. Gẹ́gẹ́ bí Olúmúyìwá ṣe fihàn nínú *Oko Aga*:

> Iṣẹ́ ẹ̀ka yìí ni láti máa ṣọ́ gómìnà lọ́sàn-án àti lóru. Eṣiṣi tàbí eèrà kò gbọdọ̀ rin gómìnà. Bí gómìnà bá fẹ́ lọ sí ibì kan, ẹ̀ka ààbò yìí ni yóò lọ fi imú fínlẹ̀ níbẹ̀. Bí ààbò ibẹ̀ kò bá péye, wọn kò ní jẹ́ kí gómìnà lọ... (o.i. 43)

Agboolé ni àwọn ènìyàn ń gbé láwùjọ Yorùbá ayé àtijọ́ ṣùgbọ́n ilé ọlọ́mú-dọ́mú-ìyá-rẹ̀-gbé ni wọ́n ń gbé lóde-òní. Èyí ló sì fà á tí ẹbí kéréje kọ̀ọ̀kan fi ní láti ṣètò ààbò fúnrarẹ̀ dípò èyí tó jẹ́ àjùmọ̀ṣe àpapọ̀ àwọn tó ń gbé ní agboolé. Bí a bá wo *Ọjọ́ Burúkú*, a ó ṣe àkíyèsí pé ẹbí kọ̀ọ̀kan ló ń kíyèsára nípa ètò ààbò ilé wọn. Ọkọ pàṣẹ fún ìyàwó rẹ̀ láti má máa ṣí ilẹ̀kùn ilé sílẹ̀, kí ó sì rí i pé títì gbọingbọin ni ilẹ̀kùn ẹnu-ọ̀nà àbáwọlé wà nígbà gbogbo. Àìkọbiara sí ìkìlọ̀ tó jẹ mọ́ ààbò ilé ọlọ́mú-dọ́mú-ìyá-rẹ̀-gbé yìí ló ṣokùnfà kí ọkùnrin ọ̀daràn kan ráyè rá pálá wọlé onílé tó sì ṣe ìyàwó oníyàwó báṣubàṣu nígbà tí ọkọ ìyàwó kò sí nílé. Àrokò tí òǹkọ̀wé ń pa ránṣẹ́ sí àwùjọ nínú *Ọjọ́ Burúkú* ni

pé ilé àdánìkàn gbé léwu ní àwùjọ pàápàá nítorí pé àwọn olùgbé ilé bẹ́ẹ̀ kì í sáábà rí ẹni ràn wọ́n lọ́wọ́ lásìkò ìdágìrì.

Àwọn ìdojúkọ tó wà fún ètò ààbò láwùjọ òde-òní wà lára ohun tí Olúmúyìwá pe àkíyèsí sí nínú *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́*. Òǹkọ̀wé yìí dọ́gbọ́n sọ ọ́ di mímọ̀ pé kò fi bẹ́ẹ̀ sí ètò ààbò gúnmọ́ fún ẹ̀mí àti dúkìá láwùjọ òde-òní. Òǹkọ̀wé yìí ṣe àfihàn àìsí ètò ààbò tó péye ní ọgbà ìṣeré tí àwọn èèyàn ti ń péjú wòran bọ́ọ̀lù, ó sì fi ọgbà ìṣeré Lékan Sàlámì tó wà ní Adámásingbà ní Ìbàdàn ṣe àpẹẹrẹ. Ohun kan tó kọ́kọ́ sọ di mímọ̀ ni àìṣètò ààbò tó múná dóko fún iye èrò ìwòran tí ọgbà ìṣeré náà gbà. Ó bẹnu àtẹ́ lu ìfẹ́ owó tó múmú láyà àwọn tó ń ṣàbójútó ọgbà náà èyí tó sọ pé ó ṣokùnfà kí wọ́n já ìwé ìgbaniwọlé-wòran fún ọkẹ́ mẹ́ta àbọ̀ èrò ìwòran dípò ọkẹ́ méjì àbọ̀ tí ibẹ̀ gbà. Òǹkọ̀wé fi sí àwọn èrò ìwòran lẹ́nu láti bẹnu àtẹ́ lu àwọn tó wà nídìí ètò náà:

> "Liberty ni wọn ìbá gbé ayò yìí lọ"
> "N ò mọ̀ pé óò wí bẹ́ẹ̀ o, kì í ṣe irú ayò
> pàtàkì yìí ló yẹ kí wọ́n fi sí Lékan
> Sàlámì".
> "Ṣé wọn ò mọ̀ pé Adámásingbà ò
> gbaàyàn tó bẹ́ẹ̀ lọ ni?"
> "N bí kí Ọlọ́run ó gbani lọ́wọ́ àwọn
> aláṣẹ wa ni" (o.i 1).

Àìkọbiara sí iye èrò ìwòran tí àwọn tó wà nídìí ètò gbà kó wọlé láti wo aré bọ́ọ̀lù náà ṣe àkóbá ńlá fún ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ènìyàn tó lọ wòran ní pápá ìṣeré náà. Òǹkọ̀wé yìí tún jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé kò sí ètò ààbò tó péye fún ọkọ̀ àwọn òǹwòran, èyí ló sì jẹ́ kí

àwọn olè ajọ́kọ̀gbé jí 'volvo' ọ̀kan nínú àwọn òǹwòran lọ. Ìpèníjà ni òǹkọ̀wé yìí fi ọ̀rọ̀ nípa ṣíṣe ètò ààbò tó péye níbi tí ọ̀pọ̀ ènìyàn yóò péjọ sí ṣe fún àwùjọ.

Onírúurú ète ni àwọn ọ̀daràn tó fẹ́ dojú ètò ààbò rú láwùjọ máa ń ta kí ọwọ́ àwọn agbófinró tó wà nídìí ètò ààbò àwùjọ má bà á tẹ̀ wọ́n. Ìṣọwọ́wọṣọ àwọn tó ń ṣọ́ ilé Bánjí nínú *Ká Rìn, Ká Pọ̀* kọ́kọ́ jẹ́ kí wọ́n jọ ológun (o.i 90). Àwọn ọ̀daràn kan nínú ìwé náà tún lo ayédèrú nọ́ńbà ọkọ̀ láti fi tan àwọn ọlọ́pàá tó ń lépa wọn jẹ (o.i 92) bẹ́ẹ̀ ni wọ́n lo oríṣiríṣi nọ́ńbà fóònù láti pe àwọn tí wọ́n ń dúnkòokò mọ́ (o.i 159). Bákan náà ni àwọn ọ̀daràn wọ̀nyí a máa díbọ́n wọṣọ bí obìnrin láti tan àwọn tó bá rí wọn jẹ. Báyọ̀ Akínwùmí múra bí obìnrin kí ó ba à lè rí àyè wọ ilé Lápàdé láìsí ẹni tó fura sí i. Bẹ́ẹ̀ náà ni Kádírì ṣe díbọ́n bí obìnrin láti fi tan Lápàdé jẹ nínú *Ká Rìn, Ká Pọ̀*. Bí a bá sì wo inú ìwé ìtàn-àròsọ Akínlàdé, a ó ṣe àkíyèsí pé àwọn ọ̀daràn máa ń dọ́gbọ́n dáràn lọ́nà tí kò ní jẹ́ kí ẹnikẹ́ni fura sí wọn. Òǹkọ̀wé *Oyin Inú Àpáta* fi hàn pé àwọn ọ̀daràn ló kọ́kọ́ máa ń yìnbọn sí ọlọ́pàá tó bá fẹ́ yẹ̀ wọ́n lọ́wọ́ wò, wọn a sì máa tipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ pa àwọn tó ń bójútó ètò ààbò àwùjọ.

## Ojúṣe àti ipa àwọn tó ń ṣàmójútó ààbò

Àwọn tó ń bójútó ètò ààbò orílẹ̀-èdè Nàìjíríà máa ń tẹpẹlẹ mọ́ bí ààbò yóò ṣe wà ní gbogbo ìlú tó wà níbẹ̀. Wọn a sì tún máa ṣètò ààbò láti rí i pé orílẹ̀-èdè mìíràn kò wá kógun jà wọ́n. Ìsọ̀rí àwọn ènìyàn tí ìjọba gbà láti máa bójútó ètò ààbò ni ọlọ́pàá,

jagunjagun, àwọn aṣọ́bodè, àjọ tó ń gbógun ti òògùn olóro àti àwọn fọ́gbófọ́gbó tó ń bójútó ètò ààbò igi. Bí ìsọ̀rí ẹ̀ṣọ́ wọ̀nyí àti àwọn àjọ mìíràn tó ń kún wọn lọ́wọ́ kò bá ṣe iṣẹ́ wọn bí iṣẹ tàbí bí ipa wọn kò bá ká iṣẹ́ tí a gbé lé wọn lọ́wọ́, ètò ààbò orílẹ̀-èdè yóò yingin, wàhálà, ìdààmú àti rògbòdìyàn yóò sì gba tilé-toko. Bí èyí bá sì wáyé, yóò dí ìdàgbàsókè orílẹ̀-èdè lọ́wọ́.

Àwọn ọlọ́pàá ni ó súnmọ́ àwọn aráàlú jù nínú àjọ tó wà nídìí ètò ààbò nítorí pé àwọn ló máa ń ṣe àmójútó ètò ààbò ojoojúmọ́ ní àyíká ibi tí a bá fi wọ́n ṣọ́. Àwọn aráàlú pààpàà mọ̀ pé àwọn kan wà tí ìjọba gbà láti máa ṣe àbójútó ààbò ní ìlú. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé àwọn tó wà nídìí ètò ààbò ló lẹ́tọ̀ọ́ láti fi òfin mú ẹnikẹ́ni tó bá ń gbìyànjú láti da ètò ààbò rú. Èyí ni Fátùrótì sọ di mímọ̀ nínú *Bọ̀bọ́ Àlútà* nígbà tí ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ sọ pé:

> Ẹ má jẹ́ ká fọwọ́ ara wa dá sẹ̀ríà fún kinní ọmọ ìrankíran yìí...Níwọ̀n ìgbà tí àwa kì í ṣe ọlọ́pàá tàbí ṣójà, ẹ jẹ́ ká fà á lé àwọn agbófinró lọ́wọ́, kí wọ́n fúnra wọn dá sẹ̀ríà fún un... (o.i 125)

Òkédìjí náà pe àkíyèsí àwùjọ sí i nínú *Ká Rìn, Ká Pọ̀* pé bí a bá tilẹ̀ rí aráàlú tó fẹ́ ṣe ìrànlọ́wọ́ láti ṣe olùgbàlà àwọn tó wà ní ìgbèkùn, wọ́n gbọ́dọ̀ fi tó àwọn ọlọ́pàá tó lẹ́tọ̀ọ́ lábẹ́ òfin láti tú àwọn ènìyàn tí ọ̀daràn fi sí ìgbèkùn sílẹ̀:

> ...òfin ò gbà mí láyè láti tú yín sílẹ̀. Ó yẹ kí n lọ̀ọ́ sọ fún àwọn ọlọ́pàá pé mo rí yín ni, kí wọn ó wáá tú yín sílẹ̀ (o.i 185)

Bẹ́ẹ̀ náà ni Olúmúyìwá fihàn nínú *Oko Aga* pé àwọn ọlọ́pàá ni àwọn ará ìlú ń pè bí wàhálà kan tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ààbò tàbí òmíràn bá wà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, nígbà tí pàkúté owó tí gómìnà ìpínlẹ̀ Èbìtà fún Kọ́lá tó mọ àṣírí rẹ̀ ṣe ré mọ́ Kọ́lá nígbà tí bọ́ǹbù dún ní yàrá rẹ̀ tó ti ń yẹ owó náà wò, ọlọ́pàá ni àwọn tí wọ́n jọ ń gbé ilé kan pè:

> ... Ìgbà tí ... àwọn ènìyàn mọ̀ pé yàrá Kọ́lá ni ọ̀ràn ti bẹ́ sílẹ̀ wọ́n já ilẹ̀kùn náà, òkú Kọ́lá àti àjókù owó ni wọ́n bá. Kíá, àwọn ará ilé fi ọ̀rọ̀ náà tó àwọn ọlọ́pàá létí. Àwọn ọlọ́pàá dé, wọ́n ya àwòrán òkú Kọ́lá kí wọ́n tó gbé e lọ sí ilé ìgbókùú pamọ́ sí... (o.i 53)

Bákan náà ni òǹkọ̀wé sọ ọ́ di mímọ̀ nínú *Oko Aga* (o.i 11 -18) nípa bí ọlọ́pàá ṣe ń gba ọ̀rọ̀ sílẹ̀ lẹ́nu àwọn tó bá mú ẹ̀sùn wá àti àwọn tí a bá fi ẹ̀sùn kan. Ètò ààbò nígbà ogun àti ògbòdìyàn tó lè wáyé látẹ̀yìn odi ni àwọn jagujagun máa bójútó; ṣùgbọ́n bí nǹkan bá fẹ́ dojúrú ní ìlú tí ipá ọlọ́pàá kò sì ká a mọ́, ìjọba a máa ṣètò kí àwọn ọmọ ogun orílẹ̀-èdè kún wọn lọ́wọ́ láti mú kí àlàáfíà padà bọ̀ sípò.

Àwọn òǹkọ̀wé kan kò ṣàìfi hàn pé àwọn ológun a máa da ètò ààbò ìṣèlú orílẹ̀-èdè rú nígbà tí wọ́n bá gba ìjọba lọ́wọ́ àwọn olóṣèlú gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú *Pelemọ* tí Débọ̀ Awẹ́ kọ. Àtubọ̀tán irúfẹ́ ìṣèjọba yìí ni àìbàlẹ̀ ọkàn tí òfin tipátipá tí ológun ṣe máa ń kó bá aráàlú àti ìfàsẹ́yìn ètò ọrọ̀-ajé wọn. Ní kété tí ètò ààbò bá ti tún wà ní sẹpẹ́ ni àwọn ológun yóò padà sí bárékè wọn. A rí ipa tí àwọn àjọ tó ń gbógun ti òògùn olóró máa

ń kó láwùjọ nínú *Oko Aga* (o.i 5 -7). Bó tilẹ̀ jẹ́ pé àjọ yìí máa ń tọpasẹ̀ àwọn tó ń gbingbó tí wọ́n ń tagbó kiri, wọn a máa kojú ìṣòro nítorí tòògùn tìbọn ni àwọn ọ̀daràn náà máa ń fi bá wọn jà, tí wọ́n sì máa ń dá ẹ̀mí àwọn òṣìṣẹ́ náà légbodò.

Àwọn ọba àti ìjòyè ló ń bójútó ètò ààbò láyé àtijọ́ àmọ́ àyípadà ńlá ló ti dé bá èyí láyé òde-òní. Ààrẹ tó jẹ́ olórí orílẹ̀-èdè ló máa ń ṣe ètò ààbò orílẹ̀-èdè pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn ọmọ ogun àti ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè tó máa ń wà ní ìgbáradì nígbà gbogbo láti dáàbò bo orílẹ̀-èdè lọ́wọ́ ìdágìrì ogun. Ààrẹ orílẹ̀-èdè ló pàṣẹ fún ọ̀gá àgbà yán-ányán fún àwọn ọlọ́pàá láti wá nǹkan ṣe sí ètò ààbò ìlú nígbà tí ìpànìyàn, ìlọ́nilọ́wọ́gbà, ìdigunjalè àti ìjínigbé gbòde kan nínú àwọn ìlú tí a ṣe àfihàn rẹ̀ nínú *Oko Aga*. Gómìnà ló máa ń bojútó ètò ààbò ní ìpínlẹ̀ rẹ̀ ṣùgbọ́n a máa bẹ̀bẹ̀ fún ìrànlọ́wọ́ Ààrẹ bí ipá rẹ̀ kò bá ká a. Irúfẹ́ ètò ààbò yìí ni òǹkọ̀wé ṣe àfihàn rẹ̀ nínú *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* nígbà tí Gómìnà Ọlátúndé ìpínlẹ̀ Ayénígbà sọ pé:

> ...Emi ni aláàbò àgbà ní ipínlẹ̀ yìí (o.i 22).

Ọ̀gá àgbà ọlọ́pàá ló máa ń rán àwọn ọlọ́pàá tí yóò ran gómìnà lọ́wọ́ láti bójútó ètò ààbò ní ìpínlẹ̀ rẹ̀. Bí Gómìnà bá sì kọminú sí irú ọ̀gá ọlọ́pàá tí wọ́n gbé wá láti bá a ṣètò ààbò ní ìpínlẹ̀ rẹ̀, Gómìnà bẹ́ẹ̀ lè fi èhónú hàn ṣugbọ́n Ààrẹ lè tako ẹ̀hónú bẹ́ẹ̀ kó má sì fọwọ́ sí ṣíṣe àyípadà irú ọ̀gá ọlọ́pàá bẹ́ẹ̀. A rí àpẹẹrẹ èyí nígbà tí Gómìnà pè fún kí wọ́n gbé Kọmíṣọ́nà Ìdòwú tó jẹ́ kọmíṣọnà ọlọ́pààbìnrin àkọ́kọ́ lọ ṣe àkóso àjọ ọlọ́pàá ìpínlẹ̀

Ayénígbà lọ nínú *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* ṣùgbọ́n Ààrẹ kò faramọ́ àbá náà. Ó sì sọ pé:

> O ò ṣe jẹ́ kí á fi àwọn ọlọ́pàá sílẹ̀ kí wọ́n ṣiṣẹ́ wọn. Ọ̀gá àgbà ọlọ́pàá mọ ohun tí ó tọ́ láti ṣe... (o.i 23).

Lára ìgbésẹ̀ tí kọmíṣọ́nà ọlọ́pàábìnrin gbé láti rí i pé ètò ààbò ìlú ní ìpínlẹ̀ Ayénígbà kò yingin lábẹ́ ìṣàkóso rẹ̀ ni pé ó ṣètò ọlọ́pàá mẹ́ẹ̀ẹ́dógún tó bá a wá nígbà tí wọ́n gbé e wá sí Ayénígbà; ó sì tún pààrọ̀ ẹkùn tí DPO mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ tó wà lábẹ́ rẹ̀ wà. Bẹ́ẹ̀ ni àṣẹ tí kọmíṣọ́nà pa láti máa fi àwọn ọlọ́pàá ṣọ́ ìgboro àti ẹnu odi ìpínlẹ̀ Ayénígbà àti Iṣẹ́lowó lálẹ́, kíkọ̀ láti gba rìbá àti ṣíṣe ìpinnu láti dáàbò bo ìlú, dídá ọlọ́pàá tó ń fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú olè dúró lẹ́nu iṣẹ́ so èso rere. Òǹkọ̀wé kò ṣàìfi hàn pé ìlò oògun tún máa ń ran iṣẹ́ ààbò tí ọlọ́pàá ń ṣe ní ìlú lọ́wọ́ nígbà tí ó ṣe àfihàn bí Sájẹ́ǹtì Ọlátúnjí ṣe lò ó láti mú obìnrin gbọ́mọgbọ́mọ tó sọ ọmọ di ewúrẹ́. Bákan náà ni Ṣóẹ̀tán sọ ọ́ di mímọ̀ nínú *Oyin Inú Àpáta* pé ìrànlọ́wọ́ àwọn aráàlú tí kì í ṣe ọlọ́pàá a máa jẹ́ kí agbófinró tètè rídìí àwọn tó wà nídìí dída ètò ààbò àwùjọ rú.

Ojúṣe àwọn ọlọ́pàá ni láti bójútó ààbò ẹ̀mí àti ohun ìní àwọn ènìyàn ṣùgbọ́n lọ́pọ̀ ìgbà tí àwọn ará ìlú bá sá lọ bá wọn fún ìrànlọ́wọ́ ni wọn kì í gbé ìgbésẹ̀ láti dáàbò bo irú ẹni bẹ́ẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, nígbà tí Láídé lọ fẹjọ́ àwọn tó ń dúnkookò mọ́ ọn tó ọlọ́pàá létí nínú *Ká Rìn, Ká Pọ̀;* àwọn ọlọ́pàá ní kó máa nìṣó nílé, pé àwọn ń bọ̀ ṣùgbọ́n kò rí ọlọ́pàá kankan (o.i 57). Ó

ṣeé ṣe kó jẹ́ pé àìṣe iṣẹ́ wọn bí iṣẹ́ ló jẹ́ kí Òkédìjí ṣe àfihàn rẹ̀ nínú *Ká Rìn, Ká Pọ̀* pé àwọn ènìyàn kan máa ń gbé ìgbésẹ̀ láti dáàbò bo ara wọn àti àwọn ènìyàn tó yí wọn ká. Irúfẹ́ ìsọ̀rí ènìyàn yìí a máa ní ìbọn tí wọ́n ń lò fún ààbò ara wọn. Àwọn ọlọ́pàá a tún máa fẹ́ dúnkookò mọ́ aráàlú bẹ́ẹ̀ tó bá lo ìbọn, èyí ló mú kí àwọn ọlọ́pàá tó ń ṣọ́ ìrìn ẹ̀sẹ̀ Lápàdé fi wádìí lọ́wọ́ rẹ̀ bí ọ̀rọ̀ ìbọn tó yìn ṣe jẹ́, Lápàdé sì fèsì pé:

> ...emí ni mo yìnbọ́n, ìbọn ara mi ni mo sì yìn. Ó dà bí ẹni pé àwọn ènìyàn kan ń rin ìrìn ìfura ládùúgbò yìí lẹ́ẹ̀kan, òun ló jẹ́ kí n yìnbọn sókè, òfuurufú ni mo sì yìnbọn sí kó má baà lè ba ẹnì kẹni... gbogbo àdúgbò ló sì mọ rírì ìbọn tí mò ń yìn lóru lẹ́ẹ̀kọ̀kan yìí, ó fọkàn àwọn ará àdúgbò balẹ̀ ni (o.i 39)

Kì í ṣe ààrín ìlú nìkan ni ìjọba ń ṣe ètò ààbò fún, wọn á tún máa gbé ìgbésẹ̀ láti ṣe àmójútó àwọn bodè tó wọ ìlú. Débọ̀ Awẹ́ ṣe àfihàn rẹ̀ nínú *Àpótí Alákàrà* pé ìjọba ṣe ètò ààbò sí àwọn bodè tó wọ orílẹ̀-èdè láti dẹ́kun ìwà ọ̀daràn tí àwọn oníṣòwò tó ń kó ẹrù fàyàwọ́ wọlé àti àwọn tó ń kó o jáde tí wọ́n sì ń tipa bẹ́ẹ̀ ṣe àkóbá fún ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè. Àwọn aṣọ́bodè máa ń lo ìbọn ìléwọ́ fún irú ètò ààbò bodè báyìí láti lè fi kojú àwọn onífàyàwọ́ tó bá fẹ́ yọwọ́ ìjà. Dípò mímójútó ààbò bodè, òǹkọ̀wé jẹ́ kí a rí òye pé ṣe ni àwọn aṣọ́bodè tó yẹ kó mú àwọn onífàyàwọ́ ń gba rìbá lọ́wọ́ wọn lórí iye ọjà tí wọ́n rà tí wọn kò sanwó bodè lé lórí. Irúfẹ́ ìwà àwọn aṣọ́bodè yìí máa ń ṣe àkóbá fún ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè ni. Ohun kan tó tún hànde nípa ètò ààbò nínú *Àpótí Alákàrà* ni pé àwọn aṣọ́bodè kò dúró lórí ìlò

ìbọn ìléwọ́ nìkan; nítorí náà ni wọ́n tún fi máa ń lo agbára tìbílẹ̀ mọ́ ọn. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni òǹkọ̀wé *Àpótí Alákàrà* fi hàn pé ìjọba pèsè àwọn ohun èlò ìgbàlódé fún ètò ààbò ní pápákọ̀ òfuurufú. Ó fi èyí sí ẹnu ọ̀gá aṣọ́bodè tó wà ní Ìdí-Ìrókò nígbà tí ó sọ pé:

> ...Ohun tó ṣẹlẹ̀ ni pé ààbò ti wà ní pápákọ̀ òfuurufú wa. Àwọn ẹ̀rọ tí í moyún ìgbín nínú ìkarahun ti wà. Béèyàn di abẹ́rẹ́ mẹ́rù lọ́nà àìtọ́, ẹ̀rọ wọ̀nyí ó tú u lášìírí (o.i 72).

Bákan náà ni ìjọba tún ṣètò ààbò fún àwọn ilé-iṣẹ́ bí i báǹkì nípa fífi ọlọ́pàá ṣọ́ ibẹ̀ kí àwọn ìgárá ọlọ́ṣà má ba à lọ ṣọṣẹ́ níbẹ̀. Síbẹ̀ náà, a rí i pé àwọn ọ̀daràn kò bẹ̀rù ètò tí ìjọba ṣe yìí nítorí wọ́n ń gbé ìgbésẹ̀ láti ja báǹkì lólè gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú *Ìṣújú Ọ̀sànyìn, Oko Aga* àti *Oyin Inú Àpáta*. Ètò ààbò tí báǹkì Ọlọ́wọ́ajé ṣe láti ní àkọsílẹ̀ gbogbo àwọn tó ń bá wọn dòwò pọ̀ ni àwọn kan dojú rẹ̀ rú nínú *Ká Rìn, Ká Pọ̀*. Síbẹ̀ náà, ìwé tí Ẹgbẹ́ Ìgbàlódé fi ṣí àkáǹtì ní báǹkì kan ní Ìjokòdó pòórá lọ́nà tó kọni lóminú. Bí a bá wo *Oyin Inú Àpáta,* pípèsè tí ìjọba pèsè ọ̀pọ̀ ẹ̀rọ ààbò ìgbàlódé sínú ilé ìfowópamọ́ tó wà ní ìlú Atẹ̀pà kò dí àwọn olè lọ́wọ́ láti fọ́ ọ àti láti pa gbogbo òṣìṣẹ́ ibẹ̀. Ìpènìjà ńlá ni èyí jẹ́ fún ètò ààbò ẹ̀mí àti dúkìá àwọn aráàlú bẹ́ẹ̀ ni àwọn òǹkọ̀wé ń sọ ọ́ di mímọ̀ pé irúfẹ́ ìfipájalè náà ń ṣe àkóbá fún ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ tí a ṣe àfihàn rẹ̀. Wọ́n sì ń dọ́gbọ́n fi èyí pe àwọn aláṣẹ níjà láti gbé ìgbésẹ̀ gúnmọ́ tí yóò jẹ́ kí ààbò tó péye wà fún ẹ̀mí àti dúkìá àwọn aráàlú.

Bí àwọn ọlọ́pàá àti àwọn aṣọ́bodè ṣe ń gbé ìgbésẹ̀ láti bójútó ààbò ibi tí a fi wọ́n ṣọ́ láwùjọ náà ni onírúuru ìsọ̀rí ọ̀daràn mọ̀ pé ohun tí wọ́n ń ṣe lòdì sí òfin, wọ́n sì ń sa ipá wọn láti ṣe ètò ààbò tó dájú fúnra wọn kí wọ́n má ba à kó sí páńpẹ́ ọba. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, Kòkúmọ́ tó ń ta ìyẹ̀fun olóró ní akọ́dà tó kọ́kọ́ máa ń fọ̀rọ̀ wá àwọn tó bèèrè rẹ̀ wá lẹ́nu wò kó tó fún wọn láyè láti rí i nínú *Taa L'ọ̀daràn?* Ẹrọ ìbánisọ̀rọ̀ ni ó fi ń bá ọ̀gá rẹ̀ sọ̀rọ̀ nípa àwọn tó fẹ́ rí i. Bákan náà ni àwọn ọ̀daràn bí Kòkúmọ́ fúnrarẹ̀ tún ṣètò pé ẹni tó bá ní àdéhùn nìkan ló lè kọ́kọ́ wọlé rí i, kó tó gbà kí ẹlòmíràn tó bá onítọ̀hún wá wọlé. Òǹkọ̀wé sọ ọ́ di mímọ̀ pé:

> ...torí bí agbèfọ́ba bá ń bọ̀ wá a mú Kòkúmọ́ ló jẹ́ kó fi ẹnìkan síta kó lè ba á ṣe alamí fún un tí yóò fi fẹ̀yìn bẹ́ lùgbẹ́ látẹ̀ẹ̀kùlé. Onírúurú aago tí wọ́n ń tẹ̀ ni ẹni tó fi ṣọ́nà lójú ọ̀nà leè tẹ̀, ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú rẹ̀ ló sì ní ìtumọ̀... (o.i 40)

Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni àwọn ọ̀daràn tó lọ fọ́ ilé-ìfowópamọ́ ìjọba nínú *Ìṣújú Ọ̀sanyìn* náà ṣètò ààbò ara wọn nípa pípèsè ìbọn ìléwọ́ tí wọn ó fi yanjú ẹni tó bá fẹ́ dí wọn lọ́wọ́ lẹ́nu iṣẹ́, wọ́n sì tún mulẹ̀ láti ṣe ìkìlọ̀ fún ẹni tí ọwọ́ bá tẹ̀ láti má tú àṣírí àwọn tó kù. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn olè náà rí owó kó tí wọ́n sì tún pa ọlọ́pàá tó wà lẹ́nu àbáwọ báńkì, àwọn ọlọ́pàá mìíràn tó ya dé rí àwọn olè náà mú; wọ́n sì gbé wọn lọ sílé ẹjọ́ níbi tí adájọ́ ti dájọ́ ikú fún wọn. Síbẹ̀ náà, lára àwọn ọlọ́pàá náà ló tún gba rìbá lọ́wọ́ olè tí ọwọ́ kò bá tí wọ́n sì sọ ọ́ di ẹlẹ́rìí ìjọba. Irúfẹ́ ìdájọ́ ikú tí

adájọ́ ṣe fáwọn adigunjalè yìí wà láti fi ṣe ìkìlọ̀ fún àwọn mìíràn tí wọ́n bá ní i lọ́kàn láti da ètò ààbò ìlú rú.

Jíbọ́lá Abíọ́dún jẹ́ kí á mọ rírì ipa tí ọlọ́pàá lè kó nínú àbójútó ètò ìlú nínú *Adìyẹ bà Lókùn* nígbà tí ó sọ ọ́ di mímọ̀ pé bí rògbòdìyàn bá bẹ́ sílẹ̀ ní ìlú, àwọn ọlọ́pàá ni yóò gbé ìgbésẹ̀ láti kápá rẹ̀. Ìdí nìyí tó fi fàyè sílẹ̀ fún àwọn ọlọ́pàá ìlú òdìkejì láti wá kó àwọn afurasí ọ̀daràn tó ń da ìlú rú ní Ìyeyè lórí ẹjọ́ èké tí ọba dá lórí ilẹ̀ ìdílé Aláfárá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kíkó tí àwọn ọlọ́pàá kó àwọn ènìyàn lọ tìmọ́lé ní àgọ́-ọlọ́pàá kọ́kọ́ paná rògbòdìyàn tó wà nílùú; síbẹ̀ náà, inú àwọn aráàlú Ìyeyè kò dùn sí i pé àwọn ẹbí ẹni tó wà ní àtìmọ́lé ló tún ní láti máa ṣètò óúnjẹ fún wọn nínú àhámọ́. Ohun kan tí òǹkọ̀wé yìí ń dọ́gbọ́n bẹnu àtẹ́ lù ni pé ìjọba kò ṣètò tó péye láti ṣe àmójútó ẹni tó bá wà ní àtìmọ́lé ọlọ́pàá àti pé èyí gan-an tún lè fa wáhàlá mìíràn tí yóò ṣe ìpèníjà fún ètò ààbò àwùjọ. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni òǹkọ̀wé yìí tún bẹnu àtẹ́ lu àìsí irin iṣẹ́ tó múná dóko tí àwọn ọlọ́pàá lè lò láti máa dáàbò bo ẹ̀mí àti dúkìá ará ìlú. Bákan náà ni òǹkọ̀wé *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* pe àkíyèsí sí ìṣòro tó ń dojúkọ àwọn agbófinró bí ọlọ́pàá nígbà tí ó fi ọ̀rọ̀ sẹ́nú Kọmíṣọ́nà Ìdòwú tó ṣe àlàkàlẹ̀ ìṣòro tí kì í jẹ́ kí àwọn ọlọ́pàá lè ṣe iṣẹ́ wọn bí iṣẹ́ nígbà tí ó ń bá àwọn ọlọ́pàá ṣe ìpàdé. Ó ní:

> ... mo mọ̀ pé a ní ìṣòro ilé-gbèé fún àwọn ọlọ́pàá ìpínlẹ̀ yìí. Àwọn ọkọ gbogbo tí ó yẹ kí á máa lò fún iṣẹ́ yín ni wọn ti gun orí odó. Àwọn ìbọn àti àwọn ohun ìjà yín yòókù kò bóde mu mọ́. Bákan náà ni aṣọ àti bàtà púpọ̀

> nínú yín ló yẹ kí ìjọba ti pààrọ̀. Mo ṣèlérí pé gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni à óò yanjú kánkán (o.i 36-37).

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun èlò jẹ àwọn ọlọ́pàá níyà, ọ̀gá náà yin àwọn ọlọ́pàá abẹ́ rẹ̀ láwo, ó sì rọ̀ wọ́n kí wọ́n fi tọkàn tara ṣe iṣẹ́ ìlú kí ààbò tó péye lè wà ní ìpínlẹ̀ lórílẹ̀. Olúmúyìwá náà sọ̀rọ̀ nípa bí ìjọba ṣe kùnà láti pèsè ohun èlò fún ọlọ́pàá nínú *Oko Aga* nígbà tí ó fi ọ̀rọ̀ sí ẹnu ọ̀gá ọlọ́pàá báyìí:

> ... Àwa fúnra wa ni à ń ra ẹ̀wù wa bó bá léyìí tó gbó àti bàtà wa tó bá léyìí tó jẹ. (o.i 13)

Abíọ́dún ní tirẹ̀ wòye nínú *Adìyẹ Bà Lókùn* pé a kò lè fojú pa iṣẹ́ ìdáàbò bò tí àwọn ọlọ́pàá ń ṣe rẹ́, ó sì pàrọwà pé ìlú kọ̀ọ̀kan ló yẹ kó ní àgọ́ ọlọ́pàá tirẹ̀.

Ohun mìíràn tó farahàn nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá ni pé a rí ìgbà tí àwọn ọlọ́pàá máa ń ṣe iṣẹ́ wọn bí iṣẹ́. Nígbà tí àṣírí àwọn olùdásílẹ̀ èké tó ń fi ẹ̀sìn bojú láti rẹ́ àwọn ará ìlú jẹ tú nínú *Lórí Òkè "Saikọfilọ̀"*, àwọn ọlọ́pàá ló lọ fi àṣẹ ọba mú wọn. Ohun kan tí òǹkọ̀wé yìí fẹ́ sọ di mímọ̀ ni pé kò sí ohun tó lè dí àwọn ọlọ́pàá lọ́wọ́ bí wọ́n bá fẹ́ ṣe iṣẹ́:

> Èyí tí a ń wí yìí ti pẹ́ jù, ọ̀kan nínú àwọn ọlọ́pàá tí wọ́n dòòyì ká ṣọ́ọ̀ṣì ti yìnbọn sókè pààràpà ... Èwo ló kan ọlọ́pàá nínú wí pé ọmọ ìjọ kan dákú? ... bí àwọn ọ̀tọ̀ọ̀kùlú ṣe pàrọwà sí àwọn ọlọ́pàá tó lọ́jọ́ náà wí pé kí wọ́n jẹ́ kí àwọn olùdásílẹ̀ méjèèjì parí ìsìn kó tóó di pé wọ́n yọjú sí wọn ní àgọ́, ṣe ni wọ́n takú herihe, wọ́n ní àṣẹ gíírímọ́káì

> láti òkè ni àwọn bá wá ... àṣẹ amúnimádàá onípàjáwìrì ni... (o.i 95 -96)

Bákan náà ni gbogbo àwọn òǹkọ̀wé tó mẹ́nuba ọ̀rọ̀ nípa ètò ààbò nínú iṣẹ́-ọnà wọn sọ ọ̣́ di mímọ̀ pé àwọn ọlọ́pàá ló máa ń ṣètò bí àwọn tí wọ́n fi àṣẹ ọba mú yóò ṣe jẹ́jọ́ nílé-ẹjọ́ ìgbàlódé.

## Àgbálọgbábọ̀

Ìjáfara léwu. Gẹ́gẹ́ bí àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá ti ṣe afihàn rẹ̀ nínú iṣẹ́-ọnà wọn, kò yẹ kí ẹnìkan, ẹbí, àdúgbò, ẹgbẹ́ tàbí ìlú fi ọ̀rọ̀ ààbò jáfara rárá. Ó hàn gbangba nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá pé ọmọ tó bá ṣípá ni a ń gbé; èniyàn tàbí ìsọ̀rí ènìyàn tó bá wà ní ìmúrasílẹ̀ nìkan ló lè dojúkọ ìdágìrì ìpèníjà olè tàbí oríṣi ìpèníjà mìíràn tó lè ṣe àkóbá fún ìṣọ̀kan àti àlàáfíà ìlú. Àrokò ni eyí ń pa fún àwùjọ òde-òní láti má fojú rénà ohunkóhun bó ti wù kó kéré tó tó le dà wọ́n lágbo nù, tó sì le ṣe àkóbá tó lè dá rúgúdù sílẹ̀ fún aláfíà tó jọba ní ìlú tàbí orílẹ̀-èdè kan. Àrokò ńlá mìíràn tí àwọn oníṣẹ́-ọnà ń pa ránṣẹ́ sí àwùjọ ni pé kò sí bí ogun ṣe le tó nípa oríṣiríṣi ìdojúkọ tó ń ṣèdènà ọ̀rọ̀ ààbò lórílẹ̀ tí ogun bẹ́ẹ̀ kò ní rọ̀. Bí á bá fojú èyí wo ìpèníjà ìdágìrì ìdigunjalè, ìjínigbé, ìfipá-bóbìnrin-lò àti onírúurú ìwà ọ̀daràn mìíràn tó gbòde kan láwùjọ òde-òní, a ó rí i pé bí àwọn aráàlú àti oríṣiríṣi ìsọ̀rí àwọn agbófinró bá fọwọ́sowọ́pọ̀ tí wọ́n sì ní ìpinnu àti ìforítì, dandan ni ogun ìjínigbé àti àwọn ìwà ọ̀daràn mìíràn tó ń bá ètò ààbò fínra láwùjọ yóò di àfiséyìn tí eégún ń fiṣọ. Ó lè pẹ́ kí èyí tó ṣeé ṣe ṣùgbọ́n ìdánilójú wà pé bó pẹ́, bó yá, yóò ṣeé ṣe. Nítorí náà,

orílẹ̀-èdè tí àwọn onísùnmọ̀mí ń gbógun ti ètò ààbò níbẹ̀ kò gbọdọ̀ sọ ìrètí nù. Dípò bẹ́ẹ̀ ṣe ló yẹ kí wọ́n túbọ̀ múra gírí láti dojúkọ àwọn ìsọ̀rí ènìyàn tó fẹ́ da àgbo ètò ààbò orílẹ̀-èdè nù. Bí a ó bá sì ṣe èyí, a kò gbọ́dọ̀ fọwọ́ òsì júwe ilé baba ẹni kí a sì máa wá baba mìíràn lọ. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní ààbò ara ẹni lààbò ìlú. Gbígbọ́ èdè àyíká ibi tí a ń gbé ní agbọ́yé ṣe pàtàkì fún ààbò ara ẹni. Ìdí nìyí tí a fi ní láti gbé oríṣiríṣi ètò ìtanijí kalẹ̀ ní èdè àbínibí láti ṣe ìtọ́nisọ́nà nípa ọ̀nà tí a lè gbà bójútó ààbò ní àwùjọ.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Abíọ́dún, J. (1996). *Adìyẹ Bà Lókùn*. Ìlọrin: Majab (Nigeria) Publishers Ltd.

Adébọ̀wálé, O. (1991). "Crime and Society: The Yorùbá Playwrights Approach", *The Nigerian Journal of Social Science and Humanities*, Vol. 1, No. 1: 30 – 35.

Adébọ̀wálé, O. (1995). "The Detective in Yorùbá Crime-Fiction". *ỌLỌ́TA: Journal of African Studies*, Ado-Ekiti. Vol. 1, No.1: 60- 68.

Adébọ̀wálé, O. and Adejumo, A.G. (1996). "Ipò àti Ipa tí obìnrin kó nínú ìtàn-àròsọ ajẹmọ́-ọ̀ràn dídá", *Inquiry in African Languages and Literatures*, No. 1: 66-77.

Adéjùmọ̀, A.G. (1999). "A Comparative Review of Yorùbá Crime Novels", *ODU: A Journal of West African Studies*.

Adékẹ́yè, F. B. (2008). *Kò sí Látẹ.* Ìlọrin: Jodola Printer & Publisher.

Adéoyè, C. L. (2005). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Plc.

Adéṣígbìn, B. C. (1998). *Ọjọ́ Burúkú*. Ìbàdàn: Ayus Publishers.

Adéyẹmi, L. (2008). *Kò Sáyè Lááfin*. Ògbómọ̀ṣọ́: Villax Inc.

Ajékìígbé, T. (2012). *Ọ̀gá Tíṣà*. Ìsẹ́yìn: Tomajek Imagination.

Akínbóyè, S. (2011). *Ọ̀tafàsókè!* Ìbàdàn: Jet Prints.

Akínlàdé, K. (1985). *Ṣàǹgbá Fọ́!* Ìbàdàn: Paperback Publishers.

Àmọ̀ó, A. (1978). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè*. Ìbàdàn: Evans Brothers (Nigeria Publishers) Limited.

Àmọ̀ó, A. (2010). *Àlọ́ Àpagbè*. Òṣogbo: Mabol Trust Publishers.

Awẹ́, D. (2009). *Pelemọ*. Iléṣà: Elyon Publishers.

Awẹ́, D. (2010). *Àpótí Alákàrà*. Iléṣà: Elyon Publishers.

Arówóṣẹgbẹ́ (2013). ''Ojú tí Obìnrin fi wo ara rẹ̀ nínú Ewì Alohùn (Inú) Orò àti Ọdún Ìbílẹ̀ Ajẹmóbìnrin ní Ẹkùn Àríwá Ìpínlẹ̀ Oǹdó". *Yorùbá Gbòde: Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àṣà Yorùbá, Nàìjíríà.* Vol. 7, No. 2: 92 -108.

Bámidélé, L.O. (2000). *Literature and Sociology*. Ìbàdàn: Stirling-Horden Publishers Nigeria Limited.

Fálétí, A. (1978). *Ogun Àwítẹ̀lẹ̀.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Fámojúrọ̀, A. (2005). *Ọmọlanke*. Ìbàdàn: Extension Publications Limited.

Fátùrótì, O. (2005). *Bọ̀bọ́ Àlútà*. Lagos: Káróunwí Publishers.

Fátùrótì, O. (2012). *Lórí Òkè "Saikọfilọ́"*. Ilé-Ifẹ̀: Adégbìtẹ́ Printers.

Ìṣọ̀lá, A. (1998). *The Modern Yorùbá Novel: an Analysis of the Writer's Art*. Ìbàdàn: Heinemann Educational Books (Nigeria) PLC.

Ògúnṣínà (2013). "Ojúwòye Yorùbá Lórí Ọ̀rọ̀ Ààbò àti Ìfaradà Ẹ̀sìn nínú Ìdàgbàsókè Orílẹ̀-Èdè". *Yorùbá: Jọ́nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá*. Vol. 7 No. 2: 1 -24.

Ojúadé, B. (1997). *Taa L'ọ̀daràn?* Ìbàdàn: Rasmed Publication.

Òkédìji, O. (2008). *Ká Rìn, Ká Pọ̀.* Ìkẹjà: Longman Nig Plc.

Olúfàjọ, A.G. (1988). "Ìwà ọ̀daràn nínú Ìtàn-àròsọ Ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́". M.A Project, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀.

Olúmúyìwá, O. (2008). *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́.* Lagos: The Capstone Publications

Olúmúyìwá, O. (2012). *Oko Aga*. Àkúrẹ́: Montem Paperbacks.

Owólabí, O. (1983). *Ìṣújú Ọ̀sanyìn*. Ìbàdàn: Evans Brothers (Nigeria Publishers) Limited.

Owólabí, O. (1988). *Ọ̀tẹ̀ Nìbò*. Ìbàdàn: Vantage Publishers (Int.) Ltd.

Ọdẹ́bùnmi, O. (2010). *Kẹ́ṣinlóró*. Ìbàdàn: Widersworld Press.

Ọládàpọ̀, Ọ. (1983). *Ògún Lákáayé*. Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press & Book Industries (Nig.) Ltd.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. (2007). *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn.* Ìbàdàn: Y-Books.

Ṣóẹ̀tán, S. (2006) *Oyin Inú Àpáta*. Abẹ́òkúta: African Resource Communications.

Táíwò, A. (2013). *Ká Rìn, Ká Pọ̀*: A Novelist's Perspective on Security". *Yorùbá: Jọ́nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá*. Vol. 7 No. 2: 111-138.

Yémiítàn, O. (1970a). *Ojú Òṣùpá: Apá Kìíní*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Yémiítàn, O. (1970b). *Ojú Òṣùpá: Apá Kejì*. Ìbàdàn: Oxford University Press.